JOVIAL NAPS
Pairs (5&7) (54&9) (3&5) (1&28)
No 7 has drawn, there is 3 Sure draws in wk 35
Come before 2 p.m Saturday with N5 Cash to:
M. O. Oketona
Oke Ola-Apemu-Ikire (7xxbk?)

Imọlẹ Owurọ

Esin oro wa "IMOLE DE OKUNKUN PARADA"

UNITY NAPS
For 3 sure draws in Wk 35 try to see The Manager Unity Pools House E4/226, Gbelekale Ibadan
See him with N5 before 2 p. m. on Saturday
5 6 7 27 32

3 APR 1974

Independent Paper VOL. XI No 633 SATURDAY MARCH 30 — FRIDAY APRIL 5, 1974 4K. (KOBỌ MẸRIN)

# ỌMỌ ỌDUN MẸJỌ YIN IBỌN PA ABURO RẸ

AWỌN Ọlọpa ilu Sapẹlẹ ni Ipinlẹ Ado-Ibinni ti mu ọmọ ọdun mẹjọ kan ti nwọn fi oruko bo l'aṣiri lori ẹsun pe o yinbọn pa aburo rẹ.

Ni ilu Agbalokpe ni iha Iwọ-Oorun Urhobo ni iṣẹlẹ na ti ṣẹlẹ; awọn Ọlọpa si ti da ọmọ na duro si ọdọ wọn fun iwadi l'ori iṣẹlẹ na.

Agbọrọsọ kan fun awọn Ọlọpa sọ pe jẹjẹ ni ẹgbọn baba ọmọ na ki ibọn rẹ ti o si gbe e ti gedẹngbẹ; ti ọmọde na si wa ni ẹgbẹ kan nibiti o ti mba aburo rẹ ṣere.

Ṣugbọn nigbati o ṣe ni ọmọde na lọ si ibi ti nwọn gbe ibọn na ti si, o gbe e, o si nye ara ibọn na wo kiri. Irohin sọ pe l'ojiji, ni ibọn na dahun. Nigbati awọn enia si sare debẹ, oku ọmọ kekere kan ni nwọn ba ninu agbara ẹjẹ.

Irohin sọ pe lẹsẹkẹsẹ ni ọrọ na di ti Ọlọpa, awọn Ọlọpa si gbe oku ọmọ na lọ si ile Iwosan ilu Sapẹlẹ fun ayẹwo. Bakanna ni nwọn mu ọmọde ti nkan na ti ọwọ rẹ ṣẹlẹ, ati ibọn na lọ si ti Ọlọpa pẹlu

*ILE ẹjọ Chief Magistrate ni ilu Abẹokuta ti ju awọn ọrẹ meji kan si apapọ ẹwọn ọgbọn oṣu fun jijẹbi ẹsun ṭe nwọn ji oku obinrin kan gbe ninu iboji rẹ. Adajọ tun paṣẹ pe ki nwọn na ẹnikọọkan wọn ni ẹgba mejidinlogun.

Ọdaran kini Oluwọle Ebẹda yio lọ si ẹwọn oṣu mejila pẹlu ẹgba mẹfa.

Awọn afẹsunkanni sọ pe awọn ọdaran na hu oku Arabirin Nusiratu Agbeke ni ẹgbo ile Alakeji ni Gbagura Abẹokuta ni ọjọ kẹtala oṣu kini ọdun yi. (Ẹ o ranti pe a ti tẹ ẹ jade ninu Imọlẹ Owurọ tẹlẹ)

Nigbati Adajọ na nṣe idajọ ẹjọ na, Adajọ Ọmọ Ọba Ade Ṣijuade sọ pe o ṣe ni laanu, bẹẹ ni o si ba oun l'ẹru pẹlu pe, ọmọ araiye tun le maa f'oju oku ri rẹdẹrẹdọ lẹhin ti a ti sin in sinu iboji rẹ.

Nitorina, Ọmọ Ọba Ṣijuade sọ pe oun da awọn enia na lẹbi, o si dajọ ẹwọn fun wọn.

## Jaguda ja Olorun l'ole

IROHIN lati Ipinlẹ Kwara fi ye wa pe awọn Olẹṣa ti wonu ile Ijesin Ijọ Paadi ni ilu Kaba, nwọn si ji Bibeli diẹ, awọn abẹla diẹ ati ẹrọ gbohungbohun ti nwọn nlo ninu ile Ijesin na lọ.

Irohin sọ pe ọrọ na ṣe awọn en'a ilu na ni kayeefi pe olẹṣa tun le wonu ile Ọlorun jale, ki o si tun ji Bibeli gbe.

Awọn Ọlọpa ilu na ti kesi gbogbo enia lati wa sọ fun awọn bi nwọn ba kẹfin ole ni ilu na.



Ai kini okunrin yi ṣe? Nje o ranti iru awọn yi ti a gbejade l'ọsẹ t'o kọja? O ku si yin lọwọ.

**BOON TO PRINTERS !**

This is a big opportunity for all Printers to cast their types at OGUNSINA PRINTING WORKS, 189 Adamasingba, Phone 23436, Ibadan, on our newly arrived MONOTYPE Supercasting Machine.

We cast from 6pt. to 72pt. on all faces of types, lead, Leadrules, borders, leaders etc with moderate charges

A TRIAL WILL CONVINCE YOU

—(MANAGER)
Phone 23436, Ibadan.

## ATIORO OMO ATIALA

# EWE IWOYI (5)

Ani lalfọre bọpo-bọyọ,
Iwa agidipsali
T'awọn ewe nhu to gẹ,
O yẹ ka diju
Ka fi ye wọn gidi,
Pe, b'aa ba huwa arifin
A kii tẹgbẹ rara.
Pe, bi a ba nṣagidi
Patiẹ ni i gbo mọ ni
l'ara.
E jẹ k'a sọrọ pato
F'awọn ọdọ iwoyi,
Pe, iwa eṣebeleke
Ko yẹ ọmọluabi enia,
Pe, bi a ba nlo aiye
Melọmelọ l'aa maa lọ.
Eniti yio tẹ ilẹ pẹ
Kii tẹlẹ giri—giri,
E jẹ k'ọdọ mọ pe,
Ọpọ agba mbẹ ni
dunia
Ti ko ni laari,
Ti awọn buru




De ibi pe, ni iṣeju.
Nwọn le sẹ'gi elewe
D'igi ti ko l'ewe mọ!
Nwọn le sọ
Oke gagara di pẹtẹlẹ:
Nwọn le s'ọdẹdẹ ọja
D'ibi ti ko l'eni ninu,
Nwọn le sọ 'le t'o kun
Di'le ahoro !!!
Bi ẹ ba r'enia t'o ba sọ pe
Iru wọn ko si,
E wi pe
K'oluwarẹ ko ọrọ rẹ jẹ.
Nitoripe, "aiye to!"
Enia ọmọ Oodua!
Enia tii sọ gba d'ẹgbun!
Enia ti i sọ' le ọla
d'ahoro!
Enia ti i dijumọri
Ti i s'ẹmọ ẹda n'ika!
Awọn onisọkoto pipọn
Ti i ṣ'ẹlẹtu yẹriyẹri!
Enia ọmọ Oodua!
O r'enia, oko sa!
Enia ti i wosunsun
Ti i ta epo pupa
Sinu ala alala!
Enia ti i di okuta
Si ẹru ẹni t'o fuyẹ!

Enia ti i ba ni wa iku
Ti i bi ni wa ibi!
Enia ti nṣe enia
Ti mb'enia daro!
Amọniṣẹni!
Afeimoniṣeni!
Aṣenibanidaro!
Oniruuru asebi nlanla
Ni mbe ninu aiye,
Ọpọ oṣika ẹda
L'o mbẹ ni dunia
B'enia ko ṣe gaya,
B'enia ko naani aiye
Ojo t'e ba lu pampẹ
aiye,
Yio mọ pe
Aiye buru ju iwọ lọ;
B'enia ko lugbadi ẹda ri
Ko ni i mọ pe
Eṣu kan ko si
T'o j'ọmọ Adamọ lọ
Aiye buru, aiye le.
Ṣugbọn aanu ṣe ni
Pe, ewe iwoyi
Ko mọ aiye;
Awọn majẹṣin iwoyi
Ko mọ 'yi enia
Ti a npe ni
"Enia ọmọ Oodua"
Laarin wa
Ni a ṣe nwi fun wọn
Ti nwọn ngbo ni l'ẹnu
Ṣe enia ti tirẹ ti bajẹ
Ko kọ bi ti
Elomiran bajẹ!
Ṣe, ẹni ti yio ṣebi
Ko kọ k'ẹjọ rẹ jẹbi
Ṣe, nitori oṣika enia
Ti kii rojọ ẹtọ f'oogun
L'ai ṣee sọ f'ẹmọ ẹni
Pe, ko ṣẹra nibi
Tita arugbo l'ẹnu
Ko si rin jinna
Nibi awọn nf'oju d'agba
Nitoripe aiye buru
Ọmọ aiye buru jọjọ.
Tabi, melo l'a o wi,
Melo l'a o ka
Nina ọpọ ọdọ
T'o ti gba 'salu ọrun lọ?
Melo ni majẹṣin enia
T'oṣika ẹda ti sọ di
Ero iiẹyilẹ ?
Ati pe, ni idakeji ẹwẹ,
Melo l'a o ka
Ninu ọpọ ẹdọ
T'agidi iṣu ti ran lọ
S'ọrun apapa-ndodo ?
Tabi ọpọ majẹṣin
T'iwa aibọwọfagba
Ti sọ d'ero ilẹ?
Ọpọ ko ha ti teri
Iwa aigbọran,
Iwa "oju mi da",
Iwa "oju mi la
Ati "temi ye mi"
Lọ sọrun ọsangangan!
Ani bi a ba mbeere
Taani ko le ri wi
Nipa iru ọdọ
T'iru iwa wọnyi
Ti ran lọ s'orun esan-
gangan!
Nitorina, njẹ,
Gbogbo enia pata
Ti ngbọ nasia yi,

Bi a ba mbu ọdọ
Pe, ohun t'ọdọ nṣe
Ni ilẹ wa ko dara,
Ti a si nsọ ẹwẹ
Ti a aki wọn ailọ,
Nitori omiran kọ,
Nitori ilẹ yi
Lẹhin - wa ọla ni
Nitori ko nii dara
Bi digbolugi enia
Ti ko gba pe elomiran
gbọn
Gori alefa,
Bi bẹẹ kọ,
Nwọn yio fọn wa n'ikun
Ati ni pataki,
Nitori ofo ẹmi,
Nitoripe, ọpọ enia
Ni mbẹ ailẹ wa
T'o jẹ pe
B'ẹmẹde ba ri i fin
Iya ọmọ na yio ṣofo,

OLOLA ATIORO





Aworan ẹgbẹ yi nṣe afihan agbayanu baalu ilẹ Gẹẹsi kan ti njẹ Concorde 002 ti o nsare bi ele—nmọ.

**27**

**28**

## IDUPẸ

GBOGBO idile Bankọle oke Apakee Ogbomọṣọ, dupẹ pupọ lọwọ awọn Ijo Onitẹbomi Kini, Jos. Alufaa Badejogbin, awọn ẹlẹsin Kristi, Musulumi, ọmọ Taraa t'o wa ni Jos awọn oṣiṣẹ ile iṣẹ Owodunni ati gbogbo enia t'o ba wa kẹdun nigbati ọmọ wa Esekiel Oyetunde Nkanlola Ajani ṣe alaisi ni Jos. Ọjọ rere l'ẹ o fi gba o, Amin.

J: C: Ajani Bankọle
(Fun ẹbi Bankole):

## IJO EGBE

AWA Ẹgbẹ Onigeolu Ogbomoṣọ pe gbogbo enia sibi ijo ẹgbẹ wa ti a o jo ni Ode Abegunde, Baaki Ogbomọṣọ l'oni 30:3:74

Aalga okunrin fun ijo na ni Ojo Babalọjẹ; Alaga Obinrin ni Feṣiyun Iya Ijẹṣa Isomogbe Wahabi Saka Aolaluwarika, Lasisi Otukoko ati Ramọta Jimo,

Baba Ẹgbẹ Isaiah Oluranti, Iya Ẹgbẹ Serah Ẹlemoso. Alaga Ọkunrin Riami Sadiku, Alaga Obinrin Bintu Adunni, Akowe Alice Popoọla:

JOHN BAMIDELE
(Fun Ẹgbẹ)

# ase Fun Irugbin Aisododo



WOLI S I. OWOẸYẸ
Onkwe ...

"ẸNITI o ba fun irugbin aiṣedodo yio ri asan ka: ọpa ibinu rẹ yio jasi ofo" — Owe 22, 8.

Ani, melo ni ọmọ enia ti o wa l'aiye ti o je olododo, bee ni ojoojumo ni iya aiṣododo nje omo enia ninu aiye:

Ṣugbon o ṣe ni laanu pe, bi iya aiṣododo ti nje eke ninu omo enia to, ọpọ awon eke ti ki ba tun yipada kuro ninu iwa aiṣododo won ko tile janpata lati yipada ki iya aiṣododo le dekun lati maa je won.

Iru awọn enia bayi ni kii fi iṣubu ati iya ti o ti je alaiṣododo ṣaaju wọn kẹkọ rara, Kaka bee, nṣe ni awọn pelu ngogo ninu iwa eke si i ti nwọn si ndagba si i ninu iṣe buburu,

Nipa bayi, awọn eke enia ko dinku mọ, nṣe ni nwọn npọ si i ti olododo si nkere n'iye. Nipa bayi ẹwẹ, awọn t'o jẹ olododo bẹrẹ sii bimọ si ile eke!

Njẹ awọn eke ha le dinku bayi? Nitorina ẹnyin ọmọ enia, emi nke ni ohun rara pe, "Igi buburu ko le so eso rere bẹẹ si ni igi rere ko le so eso buburu." Ṣugbọn emi mbi ẹ, igi rere ni iwọ fẹẹ jẹ ni tabi igi buburu?

Ṣugbọn jẹ ki o ye ọ l'oni pe, nitootọ ni eke enia le ni ohun meremere aiye yi l'ọpọlọpọ ki o si wa ni ipo nla pẹlu. Ṣugbọn ṣa o, owo ti iru ẹni bẹẹ ba kojọ nipa aiṣododo, eke ni yio fi ra bi o ti wu ki o ri, igbẹhin gbogbo rẹ yio si jẹ ibanujẹ fun un.

Nigbati enia ba jẹ ẹnibuburu - alaiṣododo, ti o si mbinu lori iwa aiṣododo rẹ, asan ni iru ibinu na yio jasi nitori ki iṣe l'ori ododo.

irọ l'o npa o, ori rẹ l'o ngegun le.

Tabi, iwo ti gbogbe ni pe, olododo ni Oluwa, ko si le ṣi idajọ ẹnikẹni lai fi ododo ṣe e. Oun yio ha ja fun alaiṣododo enia bi? Rara o, Oluwa wa ki i ja ija eke.

Ṣugbọn, olododo ni-mẹegun.

Nitorina, ri i pe ibinu rẹ si ọta rẹ jẹ ododo gẹgẹbi iwe Orin Dafidi ti o ni idaniloju ninu ọkan ara rẹ ti wi pe, "Ṣe idajọ mi Oluwa Ọlọrun mi gẹgẹ bi ododo rẹ, ki o ma si ṣe jẹ ki nwọn ki o yọ mi" Orin Dafidi 35, 24.

Njẹ, iwọ Onigbagbọ, iwọ awọran Ọlọrun, ti o lọ si ilẹ okeere lọọ jale, ti o ko ẹru ẹlẹru, ti o pada de ilẹ ti ara rẹ tan ti o sọ pe iwọ ko fẹ ki iya kankan jẹ ọ ninu aiye, nitorina iwọ yio kepe Ọlọrun lati maa wa gbija rẹ, o ntan ara rẹ ni o

Tabi, o ti gbagbe ni pe, irugbin aiṣododo ni iwọ fun si ile ibiti iwọ ti ko ẹru eleru? Dajudaju adura rẹ yio di irira, iwọ yio si ri asan ka.

(Woju Ewe Keje)

LATI ỌWỌ WOLI S I OWOẸYẸ

Njẹ, iwọ ọmọ enia ti o npa ọmọnikeji rẹ lẹkun; o ko si ronu pe iya ni o fi njẹ ọmọnikeji rẹ, ṣugbọn lẹhinna ti wahala waa de si ọ gẹgẹ bi ere iṣẹ ọwọ rẹ, ti o waa lọọ gbe Bibeli, ti o ngbadura pe, ki Oluwa gbogun ti awọn ti ngbogun ti ẹ, ki O fija fun awon ti mba ọ ja, araa rẹ l'o ntan jẹ o.

Tabi, iwo ti gbagbe ni pe, aiṣododo ati iwa ika inu rẹ l'o mba ọ jagun? Nigbati ẹsan de ba o tan, iwọ wa ngegun le "ota" rẹ l'ori, kan, ẹniti o nfi ododo sin Oluwa Ọlọrun rẹ, ti o si npa ọrọ ati ofin Ọlọrun rẹ mọ, ti ọta si nṣe inunibini si, oun ni Ọlọrun yio gbe nija.

Ani enia ti o ba jẹ olododo bayi ti ọta si nṣe inunibini si, ẹni na l'o tọ lati binu nitoripe olododo ni oun iṣe. Nigbana bi o ba sọ pe ki ohunkohun ṣelẹ si ọta rẹ, nipa idaniloju ni ọkan ara re pe oun ko se alaiṣododo si iru ọta bẹẹ ti o nwa ipalara oun, Iṣẹ aniani' ọta iru ẹni bẹẹ kẹran aṣa-

# Ọmọ Ẹgbẹ Imọlẹ Owurọ

| | | | | | |
|---|---|---|---|---|---|
| 10,629 | Tunde Babayemi, Eko | 10,640 | Kehinde Ọla Kano | 10,642 | Akinkuami Ayoade, Ogbomọṣọ |
| 10,630 | Musibawu Ajao Eko | 10,641 | Abel Binuyọ, Kwara | | |
| 10,631 | Mathew Ọlaitan, Muṣin | | | | |
| 10,632 | Taiyewo Ọladeji, Ibadan | | | | |
| 10,633 | Taiwo Ṣanusi, Ibadan | | | | |
| 10,634 | Moyebi Oyetoyọ, Ṣomolu | | | | |
| 10,635 | Isọla Salawu Ibadan | | | | |
| 10,636 | Sule Ṣitu, Eko | | | | |
| 10,637 | Abiọdun Makinde, Eko | | | | |
| 10,638 | Alhaji Ọla Iya, Kano | | | | |
| 10,639 | Taiwo Adeyemọ, Fiditi | | | | |

FUN IGBEGA EDE ATI AṢA YORUBA
DI
**Omo Egbe Imole Owuro**
(Iwe Idi omo Ẹgbẹ)

Oruko rẹ ______________________

Adirẹsi rẹ: ______________________

Ọmo ilu ti o jẹ: ______________________

Jawe yi ki o si pootu rẹ si
DOKUN AJADI
(Akowe Ẹgbẹ)
P. M. B. 5230, Ibadan



Aworan oke yi nṣe afihan Aramọbinrin Ọbabinrin ile Geesi Ọlọla Anne ni ọjọ igbeyawo re pelu Ọgagun Mark Phillips. Woju ewe kefa fun irohin ohun ti o ṣele si wọn.

# Ọjọ ibi Ademola dun

Ẹ̀au ko gba irohin ni ayẹyẹ ajọdun ọdun keji ti Johnson Ademola Ido wu ṣe ni ile wọn ni Yemetu Kanbi nilu Ibadan laipẹ yi.

Ọpọlọpọ ọrẹ ọmọ na ti nwọn waa ba a ṣe ọjọ ibi rẹ na ni o fi ẹbun oniruuru ta a l'ọrẹ bẹẹni awọn ọrẹ obi ọmọ na wa sibẹ pẹlu.

Ara awọn alabaaṣiye ọjọ na ni Omidan: Funmilayo, Rosanwo, Allen, Fẹmi Okunade, Jade Okunade., Funmilọla, Tunde Coker ati bẹẹbẹẹ lọ.

# OWO NI ORISUN ẸṢẸ (1)

Ni oni yi, gbogbo enia ni o nfe lati ni owo lọwọ. Ọpọ ọmọ araiye ko si kọ lati wa owo na ni ọnakọna nitori nwọn ṣa fẹẹ lowo lọwọ dandan.

Ṣugbọn, owo ni orisun tabi okunfa ẹṣẹ julọ fun ọmọ enia. Ani laiṣe aniani, owo jẹ pataki ninu ohun ti imaa mu idiwọ ba ọmọ enia lati pa ofin Ọlọrun mọ.

Kurani Suratu 63 aya 9 ka bayi pe, "Ẹyin Onigbagbọ ọdọ—do, ẹ maṣe jẹ ki awọn dukia nyin ati awọn ọmọ nyin di nyin lọwọ lati ranti Ọlọrun (eyi ni lati pa ofin Rẹ mọ).

LATI ỌWỌ ALUFAA MUDAṢIRU ALIYU

Ọwo jẹ irinṣẹ nla kan pataki ninu irinṣẹ ti Satanu nlo. Nigbati Ọlọrun ninu Kurani Sura 18 aya 46 sọ pe owo ati ọmọ jẹ ọṣọ aiye, Satanu sọ bayi pe, "Iwọ Ọlọrun, fi aṣẹ owo na ati ere—ajẹ rẹ si ọdọ mi" (Satanu,) Ọlọrun fun oun, ba oun da a si ara owo, eyi ti yio jẹ ipin ti oun, ki oun lee fi ko ọpọlọpọ enia dasi inu ina.

Satanu tun bẹ Ọlọrun pelu pe, ki owo na tobi l'oju wọn ki nwọn fi le gbagbe iku; ki nwọn tun le gbagbe pe iṣiro wa l'ọrun: Jẹ ki nwọn si sọ pe, "Gbogbo aṣẹ owo ko le jẹ tirẹ, ṣugbọn ẹnikẹni ti o ba gba ọna ọdọ rẹ lati wa owo tabi na owo gba oju ọna tirẹ, iru ẹni bẹẹ ni yio jẹ ọmọlẹhin rẹ".

Satanu tun bẹ Ọlọrun pe, o ti ṣọ oun (Satanu) di ẹni egbe ati ẹniti a o maa bu, nitorina Iwọ Ọlọrun, ọpọ fi ọla Rẹ bẹ Ọ, gbogbo iyi ti o ba le gbagbe pe o ti pin asiki ti ẹnikọọkan lọtọọtọ ti ko si le e lekun.

Satanu tun bẹ Ọlọrun siwaju pe, "Iwọ Ọlọrun ba mi fi agbara fun ifẹ owo yi titi de ọdọ awọn tii maa sọrọ Rẹ gidigidi, ki nwọn le gbagbe ofin Rẹ nipa a nu ifẹ si wiwa owo lọọ nakọna; Jẹ ki nwọn le fi ijọba ti owo bori ijọba tirẹ l'aiye."

Iwọ ọmọ iya mi nipa Islam, gbọ ọrọ ti Anọbi Muhammed (S.A.W.A) sọ pe, gbogbo awọn ijọ ni nwọn ni iyọnu, tiwọn ọmọlẹhin oun ni owo paapaa, oun si ni iyọnu ti o wa l'atubọtan aiye yi.

(Iyoku d'ẹsẹ ti mbọ)

# ABAJADE IDANWO BIBELI

IWỌNYI ni oruko awọn ti o ṣe daradara ninu Idanwo Bibeli ti o jade ninu Imọlẹ Owurọ 23:2:74.

MẸWẸẸWA

Awọn enia ti o gba mẹwẹẹwa ni: Moses Ojeleye lati Apapa, Pastor Yamakinde lati Ibadan, Emman Adeniyi lati Okeho; Mrs. Adejare lati U.C.H Ibadan, S.O. Rainbow lati Ogbomọṣọ, Oluṣọla Anjọrin lati Ibadan, S.A. Abidogun lati Ogbomọṣọ;

Akanni Akerele lati Ibadan, Pastor Opọọla lati Ẹdẹ, Matteu Akanbi lati Ibadan, Joseph Ọlajide lati Eko, A.B. Cole lati Apapa, E.A. Akinmoye lati Ibadan, Ebenezer Akanji lati Abẹokuta, Bọlanle Olutọla lati Ibadan;

R.A. Ayanwale lati Ogbomọṣọ, Amọs Alao lati Ọyọ, William Akintinde lati Ibadan. Michael Adebayọ lati Ogbomọṣọ, Timothy Awotoye lati Pamọ, M.A. Adepọju lati Ibadan, Kayọde William lati Eko. Jonathan Ọlawale lati Ilọrin, Joseph Ọtunla lati Eko ati M.G. Ajagbe lati Surulere.

MẸSAN

Awọn enia ti o gba mẹsanmẹsan ni: Latubọsun Adeniran lati Eko, Ọwọade Adewumi lati Ogbomọṣọ ati James Ọladele lati Eko

IDAHUN IBERE

Iwọnyi ni itọkasi idahun awọn ibere na:

1. Rutu Ori 1 ẹsẹ 6
2. Rutu Ori 2 ẹsẹ 19
3. Rutu Ori 1 ẹsẹ 16
4. Rutu Ori 2 ẹsẹ 13
5. Rutu Ori 2 ẹsẹ 12
6. Rutu Ori 2 ẹsẹ 20
7. Rutu Ori 2 ẹsẹ 4
8. Rutu Ori 1 ẹsẹ 9
9. Rutu Ori 3 ẹsẹ 5
10. Rutu Ori 1 ẹsẹ 8

IDANWO TITUN

1. Nibo ni Oniwasu ti sọ pe, Ranti Ẹlẹda rẹ ni igba ewe rẹ?
2. Nibo ni Oniwasu ti sọ pe, ko si ohun titun labẹ ọrun?
3. Nibo ni Oniwasu ti sọ pe, Asan ninu asan gbogbo rẹ asan?

LATI ỌWỌ J. K. KOBIOWU

4. Nibo ni Oniwasu ti sọ pe, maa fi ayọ ba aya rẹ gbe?
5. Nibo ni Oniwasu ti sọ pe, aabo ni ọgbọn?
6. Nibo ni Oniwasu ti sọ pe, Li ọjọ alaafia maa yọ?
7. Nibo ni Oniwasu ti sọ pe, Olukuluku li akoko wa fun?
8. Nibo ni Oniwasu ti sọ pe, Awọn oku ko mọ nkankan?
9. Nibo ni Oniwasu ti sọ pe, Ọlọrun ni Onidajọ olododo?
10. Nibo ni Oniwasu ti sọ pe, Opin sanju ipilẹṣẹ lọ?

Ẹ tete fi idahun nyin pẹlu itọkasi Bibeli sọwọ si: Jona Karimu Kobiowu (Onidanwo Bibeli) Mapo Christ Church, P. O. Box 8062, Ibadan.





Aworan kini ni ẹgbẹ osi yi nṣe afihan opopo kan ni olu ilu ilẹ Russia.

* * * *

Aworan keji si nṣe afihan ara ọpọ iṣẹ idagbasoke ni ilẹ na.

# Nje o mọ idi rẹ ti aadọtaleloodunrun ọkẹ 7,000,000 igo Guinness yio fi jẹ mimu loni?

Loni Aadọtaleloọdunrun Ọkẹ 7,000,000 igo Guinness ni ọmọ araiye yio ṣi, ti nwọn yio mu l'ánugbádùn.
Nitoripe ni Naigiria, ni Ireland (ibiti Guinness ti ṣẹ), ni Ilẹ Gẹẹsi, Trinidad,
Malaysia, Kenya, Cameroun, ati Ghana, nwọn npọn ọti Guinness lọwọlọwọ bayi.
Awọn enia mbeere fun Guinness lọwọlọwọ bayi.
Guinness ni ọti ti atayebaiye pọn. Jakejado aiye ni awọn enia ti mọ bi Guinness ti dara to.
Igbadun inu Guinness, agbara inu Guinness, ti di mímọ̀ fun gbogbo aiye lati bii igba ọdun s'ẹhin.
Lojoojumọ – bi ilẹ ọjọ kọọkan ti nmọ – 7,000,000 ife Guinness ni awọn enia ngbẹ̀ṣọu, ti nwọn mu l'ánugbádùn.
**Fi igo kan tirẹ kún un, k'ó di 7,000,001?**

# GUINNESS dara pupọ, fun ọ



# AJOMOGBE FẸẸ GBE ỌMỌ ỌBA



Aworan oko yi nṣe afihan Arẹmọbinrin Ọbabirin ilẹ Gẹẹsi na Ọlọla Anne pẹlu ọkọ rẹ Ọgagun Mark Phillips bi awọn ti fẹgbẹkẹgbẹ ti nwọn si nlọ s'ode ninu oko ayọkẹlẹ onifaji ti tọkọtaya wọn maa ndigbagbelade. Itu ipo yi ni awọn sọ pe awọn wa l'ọjọ ti nkan wu wọn na.

NṢE ni ọta lu mọto ayọkẹlẹ onifaji ti Arẹmọbinrin Ọbabinrin ilẹ Gẹẹsi Ọlọla Anne ati Baale rẹ Ọgagun Mark Philips wa ninu rẹ jẹrejẹre nigbati nwọn sọ pe ọkunrin kan ti o fẹẹ ji tọkọtaya na gbe dojú ibọn kọ mọto na.

Ni ọjọ 'Ru ti iṣe ogunjọ oṣu kẹta ọdun yi ni iṣẹlẹ na ṣẹlẹ nigbati tọkọtaya na nlọ si aafin Ọba. Nwọn sọ pe, okunrin na yinbọn si moto na nitori ki moto na le duro, ki o baa le ribi ji tokotiyawo na gbe ni.

Irohin fi ye wa pe enia mẹrin ninu ẹniti olori ẹjọ tokotaya na wa ni o fara gba ọta nitu ikoln na.

Ni afikun, irohin so pe, bi okunrin na ti fi ibon re da ipalya sile tan, ti wariwari si dajo awon tokotaya na, ni o pṣguuru si moto won, boya lati ji won gbe, nibe ni awon tokotaya na ti sare wonu oko won ni iberu ela.

Irohin fi kun un pe, nibi ni owo awon Ọlopa ti te okunrin na nibiti o ti ntiraka lati wonu moto na.

Ọbabinrin gan an ati Baale rẹ wa ni rinajo si Orilẹ—ede Indonesia ni akoko iṣẹlẹ na, ori ẹrọ tẹlifoonu ni ọmọ rẹ si ti fi irohin iṣẹlẹ (Woju ewe keje)

# Raji Akano d'Oloogbe

Ni aipẹ yi ni nwọn ṣe inawo oku Alagba Raji Alukoso ẹniti o ku ni ọjọ kejọ oṣu kẹta ọdun yi ni agbo ile Alukoso nilu Ibadan. Ẹni ọdun mejilelọgọrin ni iṣe

Ọpọlọpọ ọmọ ati ọmọ—ọmọ l'o gbẹhin rẹ; Ara wọn ni Sariyu Alukoso, Lamidi Alukoso, Adijatu Alukoso, Hanlatu Alukoso, Rasidi Alukoso, Sulatu Alukoso, Yẹkini Alukoso, Rafiu Alukoso, ati Mudaṣiru Alukoso

Ọpọlọpọ enia ati ẹlẹgbẹjẹgbẹ ni o wa sibi inawo oku na. Ara wọn ni Ẹgbẹ Ararọmi ti Popoyemọja ti ologbe na iṣe Balogun rẹ; Ẹgbẹ Ifẹlodun Popoyemọja ti ologbe na jẹ Baba Ẹgbẹ fun.

Ara awọn enia ti o wa sibi inawo na ni Alhaji Amusa Adeleke, Alhaji Adegoke Alao Ẹlẹran, Yesufu Iṣọla, Abogun, Lasisi Iṣọla, Lasisi Alade ati bẹẹbẹẹ lọ.


## KERE O! KERE O!!

*Bi o ba je onisowo ti o nfe ki oja re maa ta; ti o si nfe ki oja re gbajumo kari aiye gegebi iwe irohin IMOLE OWURO ti gbajumo; darapo pelu awon enia afata ti o npolowo oja won sinu Imole Owuro.*

*Fun alaye ekunrere nipa bi o se nilati se e ati iye ti o nilati san; wa sile ise wa tabi ki o kowe si:*

**Advertisement Manager**
**(Imole Owuro)**
**N4/496B Yemetu Aladorin**
**P. M. B. 5230**
**Ibadan.**

IWE IGBAELODE DARA FUPỌ

1. Iwe gbogbo Agbo Ọmọde ati Agua 10k
2 Kurani esu marun Yoruba 55k Esu kan (25k)
3. Yasin ni Yoruba (10k)
4. Zabura ati itumọ (55k)
5. Zabura Yoruba (40k)
6. Iwe Aiye Akamara (40k)
Iwe owe enia ṣoro 40k
7. Adedẹwọ (35k)
8. Iwosan Ajẹbidan Ogun enia dudu (N3); Kekere (75k)
9. Iwe ala ni nla (N1. 50)
10 Kekere(30k)
11 Iwe oogun iwosan (N1. 5) Kekere (45k)
12 Itan Anabi ati Yisa (55k)
13 English Hausa Yoruba & Ibo Registered No 410 (25k)

FI OWO ATI STAMP (5k) RANṢẸ SI:

(1) Alufa Yisa Igbaẹlode N2/394a, Odoye Adeoyo Rd, P. O. Box 3365, Mapo Ibadan.

(2)Alufa Igbaelode, Mọsalaṣi Idi Iṣin St Isalẹ Koto P. O. Box 17 Ilọrin



# Itan ti Oloye Bada pa se wa ni Kayefi

NINU iwe Imọlẹ Owurọ 5/1/74 ni oju ewe karun ni a ti ka itan kan ti Oloye S. O. Bada pa labẹ akọle "AGEKURU ITAN ILU OGBOMỌṢỌ (25).

Ninu itan ti Oloye Bada pa na ni o ti sọ itan aiye Baba wa ọwọn Ologbe Ọba Ọlatunji Elepo Keji, Ṣọhun Ogbomọṣọ. Ṣugbọn itan ti o pa na ṣe wa ni kayeefi pupọ, bẹẹni itan na jẹ ti inunibini, ti o mu ẹrifin wa, ti ko si ni ododo ninu. Bẹẹni ero tiwa ni pe, ẹnikẹni ti o ba ngbero lati jẹ opitan gbọdọ wa ododo dele kodoro, o si gbọdọ sa fun iwa fifi otitọ pamọ, ki o ma waa tẹ itan ibanilorukọjẹ, eyi ti o le bi ọmọ ibikubi fun iru opitan bee.

Ni ọna kini, a o tọka ibiti o ti sina fun nyin pe, orukọ Baba wa ni Ọlatunji Elepo, ki iṣe Latunji Elepo ti o pe e, bẹẹni ni 2/4/53 ni o gori itẹ Ṣọhun, ki iṣe 12/4/53 ti o pe e,

Ẹwẹ, lati inu oṣu keri^n ọdun 1953 ni Baba wa na ti wa l'ori itẹ titi d^e oṣu kẹta ọdun 1966-ey^i ti o fi han pe ọdun mẹtala ni o fi jọba.

Ni asiko igba ti Baba wa yi wa l'ori oye, ọpọlọpọ iṣẹ idagbasoke ni o ṣẹlẹ ni ilu Ogbomọṣọ ati awọn ohun manigbagbe pẹlu.

Diẹ ninu akanna ni: Radio wọ ilu Ogbomọṣọ, Telifoonu ni ọna irorun wolu, Ọna titun ati dida ọda si titi sele. Eto titun nipa akoso Igbimọ Ijọba Ibile waiye.

ẸKỌ

Nipa ti ẹkọ, ni akoko Baba wa yi ni ile ẹkọ Modern School waiye, Grade III Teachers' Training College waiye, Girls' High School, Ogbomoṣọ High School Yiyege patapata gbogbo akẹkọ oniwe mewa ile ẹkọ wa fun igba akọkọ ti nwọn kọ nipa ninu idanwo na.

LATI ỌWỌ ABIOYE ỌLATUNJI

Bakanna ni pe, ni akoko Baba wa yi ni idasile Theological Seminary, First Baptist Chuch ni Okelerin di atunkọ, Mọṣalaṣi Jimọ di atunṣe, Blind Training Centre waiye pẹlu.

Bakanna ni akoko Baba wa yi ni nwọn kọ Ile Iwosan gbogbogboo titun, ati atunkọ Baptist Hospital.

Ni aiye Baba wa yi ewẹ ni ina mọnamọna wọ ilu Ogbomọṣọ, Farm Settlement de, Sibo adugbo l'orukọ ati fifun ile ni nomba: Kikọ ile iṣe Bata; Kikọ ile eti ati ile Sinima.

Ni akoko Baba wa yi na ni nwọn kọ Bareke Olopa: Gbọngan t'tun fun ilu, Ile iṣe Ijọba ati ile ejọ Magistrate

Bakanna ni Banki wọlu, oafani omi ẹrọ ti o gbooro, ti awọn enia isl imaa sọ pe iwa ọmọluabi pọ lọwọ awọn ara ilu.

Siwaju si i, ni akoko Baba wa yi ni ile Naijiria gba Ominira. Ni akoko rẹ ni ọmọ Ogbomọṣọ di Olootu Ijọba Iwo—Oorun, Baba wa yi Ọba Ọlatunji Elepo Keji ni Ṣọhun ti o kọ lọ ile Aṣofin awọn Lọbalọba ni Iwo—Oorun; oun yi kanna ni Ọbabinrin ilẹ Gẹẹsi kọ fi oye dalọla.

Awọn ohun ti a tọkasi wọnyi jẹ diẹ ninu awọn ohun ribiribi ti a le foju ri ti o ṣẹlẹ l'aiye baba wa ti Oloye Bada sọ pe o kuru pupọ, ti ko si ri ohun rere kan sọ si.

Awa mọ daju pe bi ko ba si ti ẹgan nibọ o ye ki opitan le ri sọ bi o tile ṣe eyọkan ninu aduru ohun manigbagbe ti a tasilẹ wọn ni. Ki ba wa ṣe pe Oloye wa yi rinkiri ilu Ogbomọṣọ, ki yio ha ri nkan ko silẹ nipa Oba yi?

A fẹ ki o ye Oloye Bada pe, a ko ṣetan lati sọ ibiti a nre fun un lori ọrọ ibajẹrukọjẹ ti o sọ si Baba wa ninu iwe yi. A o fi ọrọ na to alagbẹjọro wa lati ni.

(Woju ewe kẹjọ)





## Ajomogbe

(Lati oju ewe kẹfa)

na to o leti

Bayi, awọn Ọlọpa ilu London ti mu ọkunrin alainiṣẹ ati alainibugbe kan Ian Ball ọmọ ọdun mẹẹindinlọgbọn ti iṣe ọmọ ibilẹ ilu London lọ sile ẹjọ lati koju ẹsun ọran na.

Aworan egbe yi nṣe afihan Obinrin agbe ara ile Laos bi o ti nkore egbẹ iresi n owo ale.

Irohin so pe awon agbe ile na ki le lo sinu oko won lowo osan ni akoko na nitori ogun ti nlo lowo ni ile won, ki bombu awon ara ilu Amerika ma baa ṣe won l'oṣe.

## Owoeye

(Lati oju ewe kẹta)

Nitoripe olododo ti iwọ ko l'enu yio ni igboiya lati sọ fun Oluwa pe, ki Oluwa ṣe idajọ gegebi ododo Oluwa, Nigbati Oluwa ba si nṣe idajọ gegebi ododo Re, yio ha fi eleṣe sile lai jiya bi?

Nitorina iwo ẹmọ enia, iwọ je olododo enia lati oni yi lọ. Emi nketantan fun ọ l'oni yi pe, Ma ṣe fi aidogba dapọ pe'u awọn alaigbagbọ, nitori idapọ kini ododo ni pelu aiṣododo? Idapọ kini imọle si ni pelu okunkun?—Kọrinti Keji 6, 14.

ADURA

Oluwa, nipa igbagbo, awa nreti ododo Re k'o le wọnu aiye wa, nipa bee ki otito ati ododo le jọba l'orile—ede wa ati ni ilu enikookan wa paapaa julọ, Oluwa je ki ododo Re jọba ninu mi ki ọrọ mi ati iṣe mi maṣe jasi ofo, Amin

# Itan Bada

(Lati oju ewe keje)

Şugbọn şa, a bẹ Olo-tu Imọlẹ Owurọ ati ẹnyin na fun atunşe itan t' ẹ pa na larin ọsẹ meji ti iwe yi ba de ọwọ nyin, bbiçẹkọ, ọrọ na-le bi ọmọ ibikubi nitori-ripe o di dandan fun wa lati tun orukọ Baba wa se"

AKIYESI

Bi o tilẹ jẹ pe ki işe pe Oloye S. O. Bada bẹ wa lati gbẹnuşọ fun oun l'ori ọrọ yi, a fẹ ki o yé Ọmọ Ọba Abioye Ọlatunji pe, Oloye Bada at ile işẹ wa ko ni inunibini si Baba wa Olorogbe Ọba Ọlatunji Elecpo Keji na a pa itan yi.

Ni ọlọa k ni, itara si pe ki o mu itan Ogbomọşọ wa si ẹ gbọ gbo-gbo aiye a pa pe lati ẹdọ ọmọ Ogbomọşọ tikalara wọn ni o bi eyi, bẹẹni ẹmi rere n' awa na ni lckan, ati bi a ṣe mọ Oloye Bada bi agba onitan ni a fi gba a l'aye l'ori nkan wọnyi pẹlu.

Şugbọn ẹ mase gba-gbe pe itan pipa ki işe ohun ti a mas ndimu bi işẹle ti o sọju onitan ti o si gbọdọ jẹ "oko-doro" dele; nitori anfa-ni "aidaniloju" yi ni aaye fi wa lati tako onitan kan, ati lati fi ohun ti awa ba mọ si otitọ rọpo itan ti oni-tan na pa, ki o si fi idajọ re s'owo onkawe. A ni ireti pe ẹ o fi iru oju bayi wo o:

A si lero pẹlu pe nipa iwe nyin yi, ẹ ti fi ododo itan tiyin mule aiye si ti ka a. Bi e ba si ni omiran si i, aaye mbe sibe. Bi ẹnyin na ba şakiyesi pe, nipa l'am Oloye Bada ni aiye fi ni anfani lati mọ siwaju nipa işẹ rere ati orire Baba wa Oloogbe na, ẹ o ri i pe, "Bi ibi ti mbe ninu ire, ni ire na wa ninu ibi"; Gbogbo re ti şişẹ pọ fun rere.

—OLOOTU

# NI IRANTI

IYA WA ỌWỌN

Madam Ibirinade Latona ti ile Latona, Osogbo ẹniti o sun ninu Oluwa ni 27:3:73, ti a si sinku rẹ ni 31:3:73.

ORIKI

Ayinkẹ Odi Mọdẹ Irẹsa
Ọmọ Şọhun l'Ogbomọşọ
Ọmọ Jogioro Makandẹ
Ọmọ afin ko k'ẹyọ
Mọdẹ Irẹsa.
Afin ki ba k'ẹyọ
M'ba ti m'ẹgbaa wọn afin lori
Ọmọ şeni-ng-o-şeni
Nil bi 'Rẹsa ninu
Bọsile—o—bu'po
Nil ya Mọdẹ l'ara
Afin ko k'ẹyọ Mọdẹ Irẹsa
ỌRUN RERE O!

Mrs. Jadesọla Fakunle

# Akiyesi Pataki

EYI ni lati sọ fun gbogbo ẹnyin onibara wa nibi gbogbo pe, a ti kuro ni ile itaja wa ti o wa ni No. 53 New Court Road, Ibadan, a si ti ko si No: 3A Fadeşire Compound, Fẹlẹyẹ Street lẹba Ruşewe Stores, Ibadan.

ALHAJI J. A. AGBỌMỌJO
(Alakoso Ile Işẹ Bata Ghana)

# OLORIRE O ! OLORIRE O !!

Awa Egbe Onisowo

## WESTERN NIGERIAN TRADING COMPANY LIMITED

TI TUN GBE ORIRE DE.
A TI GBE T'ANA DANU
A TUN GBE OMIRAN DE.
A TI NI ẸRỌ ATATA YI:



# Gari Grater

## With JLO Engine L101 (N285.00)

(EYI NI ẸRỌ TI NWỌN FI NRIN GARI OLOWOYỌ)

Aiye ti di aiye jẹlẹnkẹ,
Ko si ki a maa fi agbara wa owo mọ.
Bi o ba ti ni ẹyọ ẹrọ yi kanşoşo
Jẹ ki ọkan rẹ balẹ pẹsẹ
Nitoripe owo—olenla
Ni iwọ yio maa pa.
Owo ẹrọ na ko pọ rara
N285.00 PERE NI:

Ranti pe nigbati o ba mbọ, o nilati mu iwe irohin "IMỌLẸ OWURỌ" kan ti a polowo ọja yi si lọwọ:

Bakanna ni a tun ni oniruuru ẹrọ ati ti ilẹti "BECO" fun tita pẹlu.
A tun ni ẹrọ ifinkoko ni ile işẹ wa, owo rẹ ko si pọ.
Ranti pe igbakugba ni owo ẹrọ yi ngoke si i.
Tete yara wa ra tirẹ l'oni.
Ẹ maa bọ tẹara si

**Western Nigerian Trading Company Limited**
P. M. B, 5148; PHONE 22361/2
DUGBẸ ONIMATIẸRSI, IBADAN

PRINTED AND PUBLISHED BY THE PEOPLES' STAR ... IBADAN ...